# EKO AKETE.

## IWE IROHIN OSOSE.

ỌRỌ IFOJUSUN:—

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI".—W. T. STEAD.

VOL I. NO. 33. SATURDAY, FEBRUARY 24, 1923. FOURPENCE.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.

J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode lailai, P eti *Glover Memorial Hall (Customs Street,)* EKO.





Awọn Oyinbo Onişowo yi nranṣẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranṣẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nṣe oriṣiriṣi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranṣẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja Abọmafọ ati oriṣiriṣi ọja

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi ṣi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

*(Macaulay's Household Dispensary.)*

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-oja yi, to wa ni opopo-nla (*Broad Street*,) l' Eko ni owo po o.

Awon Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aṣẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WỌ. Ogun rẹ jẹ bi idan.

---

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nşowo Irin Işẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria,

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

## ỌGBẸNI DURO THOMAS.

ONIŞOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

## Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA.

Ọgbẹni D. B. OŞUNTOLU, onişowo Ọlanrewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Şabu rẹ ni No. 44. Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:—Ikoko taba, Carpets Panu ikọle, Aşọ oniruru, Itẹkọ, Baranjẹ, Olowonyọ, Yọmini, (*Sallen*.)

Ati orişirişi nkan atata miran, Ọja Ọgbẹni yi roju o si lere ninu, ọpọku-ọyọku ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.

---

WHAT IS MORE REFRESHIN[G] than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-savin[g] than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment o[f] Brass Iron-Beds, Bedstead[s] (new arrivals from Germany hand and Treadle-sewin[g] machines "Gritzner" is just t[o] hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!

AŞỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

AŞỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati

MASINI-A-NJUWON

Ọgbẹni DURO THOMAS.

Onişowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to şeşẹ de fun u pẹlu awọn MAŞINI iranşọ ti a npe ni *Gritzner* ti ọlọwọ ati ti ẹlẹsẹ, lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Māse leti ita Faji, l'Eko.

Ifa mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

Ẹ lọ ba Awúre nyin pade nibẹ.

## GBOHUN-GBOHUN.

———:o:———

"A-DI-NI-MỌ' DO" OBINRIN. !!!

Aṣa ki obinrin ma di ni mọ' le lo tun gb'ode kan nisisiyi. Ni werewere oju alẹ *Thursday* ọsẹ to kọja, obinrin kan ti o ro dẹdẹ ti o gba-dẹdẹ lọ sọdọ Sanmari kan lọna Opopo-nla nibi: o si ni ki Sanmanri na wa ba on san igbese kan: obinrin yi tilẹ daruko awọn diẹ ti o ni nwọn ti bo on laṣiri lọna bayi ri, bẹni Sanmari yi ko mọ obinrin na ri ki o to wọ' le gẹn-nẹ tọ ọ wa. Ṣugbọn ọwọ ti "Ojigọbi" yi wẹ ilẹ lo fi nu, nitoripe "ake" ti o mu wa lati fi "ṣa" ọgbẹni na ko murọ: iyoku di'regbe, ọna ẹburu ni alakọri na gba jade nigbati "oyi bo o tan.!

———

OJỌ NKU FẸFẸ

Ọtunla *Monday*, ni Ipade ti a sọrọ rẹ lọsẹ to kọja: agogo mọkanla arọ ni Ijọba fi si, ni Ile-iṣẹ Ilu (*Nigerian Secretariat.*) Ara ilu, Ẹ ma jafara ati lọ sibẹ: a tun tẹnumọ pe nwọn ki nmu ni silẹ nibẹ. Ẹ kalọ o, iwaju l' ero nb' ero.

———

ỌMỌ ONIKU Ẹ KU ỌFỌ.

Ọgbẹni ti a sọrọ aisan rẹ laipẹ yi, Ipaiyẹ Balogun Isalẹ-gangan, Atẹ-nla-ọran-bọ'mi gẹgẹbi oriki rẹ to wa lara ọkan ninu ferese ile rẹ l' Eko ni atijọ, ṣalaisi ni Ilu Ajebamidele ni ọjọ keji oṣu yi: awọn ọmọ rẹ si sin i, bi ẹni sin iyawo. Ki Baba foriji i.

———

ỌRỌ IKỌKỌ NI GBA-NGBA LO NBỌ.

O dabi ẹnipe ohun ti a sọ ni ọsẹ to kọja nipati awọn Akọwe John Holt fẹrẹ run awọn kan ni 'nu pe a tete kede ohun na ... ati pe boya lamọrin lo sọ fun wa: agiwi ..yi, ipo wa gẹgẹ bi Ajihin ohun ti yio ṣe, un to nge lọwọlọwọ, ati ohun to ti ṣe kọja ... wa ni aifani lati sọ bi a ti sọ: ti ..a ri ẹniti sisọ bayi ko wọ fun, ki irufẹ ..va rẹ ṣe gafara fun wa, ṣugbọn ki o tun lajupe pe ko si Igbati Maku ko ni ku!!!

———

ỌPA ỌBA, Ẹ KO KERẸ L' OYE!

A gbọ pe ninu ọduñni awọn ọga ọlọpa nilẹyi ti ntẹ iwe Iwe-irohin ti wọn ti a npe ni *Police Gazette*: a sọ pe nwọn ntẹ iwe na l' aṣiri, eyini nipe ko wa ni arọwọto fun gbogbo ilu, lati ra fun kika. Ọgbẹni-Ologun Duncan. Ẹ ba fi ọkan ninu rẹ ju wa lori, a ba yọ yọ.

———

Ẹ JAJA J' AJA.

Inu wa dun lati ri pe awọn Ijọ *Bethel* tun dide si biba iṣẹ Ile-isin wọn ni Opopo nla lọ ni kikọ: a gbọ pe ki yio tun si idaduro mọ titi Ile na yio fi pari; Aṣẹ.

———

IYAWO BORI BO 'SẸ, ALẸ ONI LA O GBE.

A gbe ọmọdan ọmọ Ọgbẹni Owen Johnson ti Ita John ni Alakoro ni Iyawo fun Ọgbẹni S. B. Anjous ti Ita Faji, ni Ile-isin Olowogbowo ni agogo mẹjọ-abọ ọjọ *Tuesday* ọsẹ to kọja: Ẹni-ọwọ E. E. Williams lo tọ wọn ni'fa oruka. Iyawo a-we gele aremọ laipẹ o.

———

ỌMỌ KO LAYỌLE ẸNI ỌMỌ SIN LO 'IPỌ.

Ko ya ni lẹnu mgbati a gbọ wipe Ṣọgi Bẹtẹli ṣe ribiribi nibi oku Daddy Cole ti apele rẹ njẹ "Jabiara" ọkan ninu awọn akuṣẹ Ijọ yi, ẹniti o ṣ'alaisi l' ọjọ Isinmi to kọja ni ile agbawo rẹ l' Oke Suru l' Eko, nitori o ṣe ndi igbagbọgbo tun ..wu yi lati ma bo aṣiri awọn akuṣẹ wọn l' a.. si ati nigbati nwọn ba lọ jẹ ipe Ọlọrun.

Anu ṣe ni nigbati a gbọ wipe ọmọ meta ni ologbe yi bi, meji ninu wọn ti f' ilẹ bo 'ra leralera, eyiti o si jẹ ẹkẹta si ti nu. Eyi lo mu oku yi jẹ ti Ijọ t' olori t'elese t' ọkunrin t' obinrin lo dide lọgan ni Ijọ Baptist Ararọmi la bẹrẹ isin oku yi, Ẹni-ọwọ Puddicombe ti Ijọ yi, si fi tifẹ-tifẹ keji Ẹni-ọwọ Akiọla titi oku fi wọ'lẹ. Ọrọ ti Ẹni-ọwọ Akiọla sọ lori oku yi ka ni lara janyin-janyin, ni gasikia o fa omi jade loju ọpọlọpọ.

*—a ro la wa nij...*

Bi iku ba nyẹni, o gba fun ologbe yi pọju, ki Oluwa fi i si afẹfẹ 're. Ẹnyin Ijọ! A ki nyin, ẹ ku inawo, ki Oluwa pese alaṣẹhinde fun ẹnyin na.

## ỌKURIN JẸJẸ ABIJA KIKUN.

A gbọ pe Sẹkitẹri agba ti Ijọba, Sir D. C. Cameron K.B.E. dide ni Ilu-Gẹsi ni ọjọ *Wednesday* ọsẹ yi, yio si ba ọkọ *Abinsi* "Ayara-bi-aṣa" de ibi ni ọjọ kẹjọ oṣu *March* to mbọ.

## ỌBA ALAṢẸ EKEJI ORIṢA

Gomina-agba nmura ati lọ si ilu oke, ati Ilu awọn Hausa, titi ọjọ keji oṣu to mbọ; a si sọ pe ti o ba pada de, yio palẹmọ ati gba isinmi lọ si'le ni ọsẹ ekinni oṣu *April* to mbọ.

## ABỌ O, BALOGUN DODO NDAWA

Igba kẹta Gomina, Ọgagun H. C. Moorhouse C.M.G. bọ lati ajo to lọ Ilọna Calabar ni ọjọ ọsẹ to kọja.

## ABỌ O.

Gomina Agba, Kinniun-onibudo ati Lọya-jiga bọ lati Ibadan ni lọlọyi.

## Ẹ KU AJALU!!!

A ba Ọgbẹni John Daniel oniṣowo Ekurọ ati aburo Ọgbẹni P. St. Matthew Daniel ti No. 8 Ita Bamgboṣe kẹdun Iku aya rẹ to ṣẹlẹ lojiji ni Lafiaji ni ọjọ *Wednesday* ọsẹ yi.

## EMI LEYI L'AIYE OBA?

Ihin kan wa ni gbukẹ pe awọn alaṣẹ Ilu Ibadan le Ọgbẹni Herbert Macaulay, C.E. kuro ni Ilu na nibiti a sọ pe o lọ siṣẹ wiwọn ilẹ fun awọn to bẹ ẹ ni iṣẹ na ni lọlọyi. A gbọ pe nwọn ko fun u laye lati sun si Ibadan, ati pe Idikọ ni Adio lo wa sun ki o to pada wa s' Eko ni arọ ọjọ keji [illegible]!!!

## What is the meaning of this under the Union Jack—The Emblem of Liberty and Freedom?

It is reported that the Ibadan authorities actually drove Mr. Herbert Macaulay C.E. away from the Country whither he went lately for survey work on professional engagement and that he was forced to seek shelter at Adio Station where he passedthe night ere his return to Lagos the following morning during this week!!!

## ṢIṢI ILE ẸKỌ GIGA TI IJỌ BAPTIST FUN AWỌN ỌDỌMỌKUNRIN.

A ṣi Ile-ẹkọ giga kan, ti o nṣe ti Ijọ Baptist, ni *Tuesday* 23rd January, ni agogo mẹrin abọ, bi eto rẹ ti lọ niyi o:—

Ẹni-ọwọ Adi-arugbo-ṣebi-omidan Pinnok, ẹniti o kọ aragba-jẹnjẹn, Ile-ẹkọ giga na, lo gba adura ṣiṣi Ile na.

Lẹhinna ni nwọn fi kọkọrọ fadaka Ile-ẹkọ na fun Ọba wa, Ademọla II, Alake ori Ẹgba. O ṣi 'lẹkun, gbogbo wa wọ ile gbọngan nla ti o wa larin Ile-iwe giga na, olukaluku joko jẹ ni ipo rẹ. Ile kun, o de kọ gbaye rara, ọpọlọpọ joko lori koriko. Lẹhin ti gbogbo wa joko jẹ tan ni ipo wa, Ẹni-ọwọ S. G. Pinnok lo kọ ṣọrọ. O sọ bi ilẹ ibiti nwọn kọ Ile-iwe giga na ti ṣe tẹ wọn lọwọ nipa agbara Alake (ti o ti ku), awọn ara Owu lo ta a fun wọn.

O gba wọn ni oṣu mẹrinla ni kikọ Ile-iwe giga ramu-ramu ti a nwi yi, owo ti nwọn na si i jẹ ẹgbẹrinla ponwun (£2,800).

Awọn oniṣọna ti o ṣe e niwọnyi, Ogunṣọla ati Ogunṣẹyẹ, awọn mejeji Kemta, Abẹokuta.

Ile ti nwọn kọ sibẹ jẹ pẹtẹsi nla kan fun *Principal* ati Alabojuto Il[illegible] na ati awọn ile ilẹ mẹta kan wa eyiti Gbọngan nla ragbaja kan [illegible] kikọ iwe.

Ẹniti o tun wa sọ oju abẹ ọrọ niko gan ni, Alabojuto gbogbo ilu C. W. Alexander Esq., B.A., L.L.B., ọrọ rẹ gun ni ni kẹsẹ, o si fun ni ni itara ati kọwe ati lati ran ọmọ wa lọ si Ile-iwe de gogoro. O ka ni lara ji i bi ṣara *Tobacco* imu.

Alake lo tun gbe, lẹsẹ ninu ọrọ sisọ. O sọ iye ọdun ti REV. and Mrs. Pinnok ti de ilẹ wa nihin (ki iṣe Abẹokuta nikan) o jẹ 35 years, ọdun marundilogoji. O ki wọn fun apọn wọn, o si tun sọ bi o ti yẹ ki a ran wọn lọwọ ninu ọna gbogbo, gbakan-nṣubu ede Gẹsi lo fi nsọ gbogbo nkan wonyi.

Ẹniti nwọn tilẹ fi gbogbo ọrọ na fun sọ julọ ni, olohun iyọ, atakere ija dun u, ogbogi ni Iwe *Prof.* Oyerinde B.A., B.D., Oluranlọwọ ọga Ile-ẹkọ giga ti ijọ Baptist ti o wa ni Ogbomọṣọ. Ko n'araru ni gbogbo ọrọ rẹ jẹ fun gbogbo awa ọdọmọde, lọkunrin ati lobinrin, l' ori ẹkọ aye, ti o si ye koro ti ko di pẹta rara.

Nitoripe ko si igbati a d'aṣọ ti a ko ri ilẹ fi wọ. Gbogbo ọrọ rẹ, gba-kan-nṣubu ede Gẹsi lo nyi silẹ rabata-rabata, pẹlu itumọ ti o ye koro. Eyiti o fi sọrọ ikan ko jọkan, o to bi iwọn ogoji iṣẹju, sibẹ, ko su u, ko su wa, Ẹni-ọwọ Pinnok lo bẹ ki o panu mọ, ki o jọwọ jẹki eyiti o ku di ijọ miran ọjọre. Nitori awọn oyinbo ti o wa larin wa, o rẹ wọn.

Ki Ọlọrun ṣi wa li ọkan, ki o si fun wa ati awọn ọmọ wa ni aye ọpọlọpọ lati fi kọ ẹkọ atata, ki a wa le ku iku olododo, ki igbẹhin wa le dabi tirẹ. O fẹrẹ to ọdun mẹwa ti *Prof.* Oyerinde lo lori ẹkọ ni Amẹrika.

K' Ọlọrun da ọ si fun wa o, *Professor* ki o si fun wa l' ọmọ ti ao fi s' ọdọ rẹ fun ye ti ki i ṣe oku Amin.

Ẹni-ọwọ S. G. Pinnok lo ko ifanfanu ọrọ o gbọn silẹ lati ẹnu *Prof.* Oyerinde, tun gbogbo rẹ to, o ṣe rẹmu. O dupẹ ọ awọn ti o fi tayọtayọ wa sibi ṣisi ile -giga yi, papa lọwọ Alake, alabojuto Ọgbẹn C. W. Alexander, igbakeji rẹ Ọgbẹni Hughes, awọn ọba wa mẹta ti o ku ati lọwọ *Prof.* Oyerinde-ẹlẹrin agbayunkun ati lọwọ ogunlọgọ enia ti o fi tinutinu wa, ninu awọn ẹniti awọn sọnmọri wọnyi wa:—

Ọgbẹni Hughes, D.O. Abẹokuta, Page-Agent Lagos Stores ni Abẹokuta, Adegboyega Ẹdun ti Niger Company, J. B. Majẹkodunmi-ọtun gbogbo Ẹgba, Adenẹyẹ Titcombe-Sẹkitẹri Alake, J. E. Smith-ọga awọn agbowo ode, Ariyọ Ṣorinolu, Ẹni-ọwọ J. J. Ransome Kuti, J. J. Olumide, N. A. O. Morgan, S. A. Delumọ, B.A., L.TH., D. A. Majẹkodunmi, Mr. ati Mrs. E. A. Kelly, S. M. Ibarẹ, Dr. ati Mrs. A. Ladipọ Oluwọle, M.B. etc. H. A. Ilori, Sam Kuforiji, Amos Williams, F. George ti ilẹṣẹ Resident oke Igbehin, Cornelius Kuforiji, B. A. L.TH., D. O. Lijadu ati ogunlọgọ enia ti a ko le daruk tan sihin, papa gbogbo Ologbeni.

Ẹni-ọwọ Pinnok tun sọ pe ki awọn s fun ọga ile Ẹkọ-giga ti Igbebin ọgbẹni Kuyẹ pe ki aya ki o maṣe ja, pe dida ti nwọn da ile Ẹkọ-giga ti nwọn silẹ, ki i ṣe lati fi gba lọmọ tabi lati ba ja, ṣugbọn lati ma fi ara we wọn ninu Iwe ti o jinna han. Ọmọ ile Ẹkọ-giga ti Igbehin ti o ba sa wa sibẹ, nwọn ki yio gba si ile Iwe-giga ti wọn.

Ole ko le ranyin igbe ni ọjọ na jẹ fun ẹniti o ba gbọ ajini pẹpẹ ede Gẹsi ti o nti ẹnu Ọba wa-Ademọla keji-Igi-owo, jade ati lati ẹnu Olohun-iyọ ati ogbogi ni Iwe *Prof.* Oyerinde, B.A., B.D., ẹni ti o ba ni ọmọ ki o kọ l' ẹkọ dada. Abọ ẹkọ l' ewu lọpọlọpọ, ọmọ ti o ba si ni anfani ati lọ si ile Iwe-dada, ọga fa, ki o maṣe ṣoṣẹ iṣa, ki o mura giri. O ko ri mi bayi ọbọgilawọ? Ki Ọlọrun jẹki a ni ọmọ ti yio ni ọpọlọpọ ti o ji perepere lati ran lọ si ile Iwe-giga yi tabi ni bomiran.

Lẹhinna a kọ ẹsẹ kan ninu ki Ọlọrun da ọba si, ipade na si pari.

Ọba, alabojuto Ilu ati awọn ọba mẹta ti o ku wo gbogbo ile Iwe-giga titun na kakiri, ati awọn Ijoye-ilu. Gbogbo rẹ nṣe yungba, atẹgun ni on atẹgun, o dabi enipẹ ki a ma ṣe kuro nibẹ, oru lo la wa nija.

...ọmọ kan ba nlọ si ile Iwe-giga na, ... o ba ni aye ọpọlọpọ dada, a fẹrẹ ṣi Iwe-... nikori atẹgun dada pọju nibẹ.

Ki Olọrun da Ẹni-ọwọ Pinnok si fun wa ati ti aya rẹ pẹlu, awọn na ti o ti lo ọdun marundilogoji larin Ilẹ awa enia dudu, ki awọn tun le lo ju bẹ lọ si i larin wa Amin.

*Abeokuta,*
*24th January, 1923.*
F. O.

---

## EKO AKETE.

EKO, SATURDAY, FEBRUARY 24, 1923.

---

### AWỌN ATU 'RỌ-TÀ BI ÈLÙBỌ́.

Ko ha jẹ ohun iyalẹnu lati ri pe awọn ...n wà ni ilẹ yi ti nwọn kò ni iṣẹ meji ju ...wọn mã sọ ohun ti ko si lọ; nipa bayi, ...lọpọ ibi ni nwọn ti ṣe ilu, iwa yi si ti ... nkan pupọ l'oku larin wa nibi: a tanma pe irufẹ awọn enia to nṣe nkan yi ko ni ju awọn ti a ba mã pe ni Owulẹ-wulẹ-da-riri lọ: ti oju ki nti lati ma so irun-iwaju pọ mọ ti ipakọ: iwa Alapa-maṣiṣẹ ti ẹlomiran ni lo nmu wọn mã yajule kiri lati mã gbe okan enia gbona nipa sisọ ọrọ ti oju wọn kò to; bẽ ha kọ ni nwọn mu ọran Eleko diju nijelo nipa irọ nla ti nwọn pa, ti o si de ẹti-igbọ Ijọba, pe Ọga awọn Gomina ni ilu Ọba ti pa laṣẹ kiakia fun Gomina Agba pe ki ọ fi Eleko pada sipo rẹ̀, ti ko ba fẹ ri pipọn oju on! bẽkọ ni awọn "Ọjẹ-d'ọlẹ" enia wọnyi nsọ kiri ni ẹnu ọsẹ to kọja pe Gomina ranṣẹ si 'le pe on npete ati wa awọn kan danu, ati pe ki Sẹkitẹri Agba ni ilu Oyinbo le fun on laṣẹ ati ṣe bẽ?

Eyiti nwọn tun fọ jo'lẹ̀ ti nwọn si njẹ-ajẹgba rẹ bi ti kọ-nkọ nisisiyi ni pe a ti fi Waya pe Gomina Agba lati Ilu-Oyinbo pe ki o mã bọ wa 'le ntoriti o ti ṣi i tẹ, nipa sisọ gbogbo ilu di rudurudu nihin,! ẹwe, a tun ngbọ kakiri pe Gomina Agba binu si Ọgbẹni Henry Carr Balẹ Ilu ati pe laipẹ, ao gbe e lọ si idalẹ!!! Ahesọ ati atusọ patapata gbã ni ọrọ wọnyi jẹ: bẽ iru nkan wọnyi ni Ijọba ngbọ ti nwọn si nka si ọtọ ti o si nmu wọn binu pe oloraye-enia pọ to "wọbu" nibiyi ti nwọn ko lọ wa iṣẹ ṣe bikoṣe ki nwọn mã dari awọn enia ribo-ribo nipa ọrọ isọkusọ wọn.

A sọ fun Ijọba ati gbogbo awọn Alaṣẹ Ilu ati awọn enia wa ti dudu ti funfun, ni'le l'oko ki nwọn maṣe nani irufẹ agbọsọ bayi mọ, nitoripe awọn ti nwọn nṣe e ni iṣẹ ko kọ̀ ki ọran ilu má bajẹ siwaju: ilù Ẹda-nlulu-ibajẹ ni nwọn nlù, ṣugbọn, Ipọ̀ri gbogbo wa ko ni jẹ ki o dun: awọn ẹlomiran wà ti o jẹ pe Irọ-pipa ati Eke-ṣiṣe jẹ ohun ti nwọn fi njẹun kiri ile-onile.

A ro pe nigbati awọn enia wa ba ka ohun ti a kọ yi, nwọn yio mọ ati mã ku eru-eke le ori ẹnikẹni ti o ba fẹ tun họrọjọ bi ologbo-idunmọta fun wọn, nipa sisọ ọrọ isọkusọ bi ẹja, lati ri bi akọ tọrọ (3d.) tabi sisi (6d.) kan gba lọwọ awọn ti nwọn ngbadun ati ma gba irọ wọn gbọ lọna yi.

Ẹ gbọ bi a ti wi ninu Iwe wa ninu ewe kẹdogun "Gbọngbọn-kosi" nipa ọrọ yi.

Iṣẹ eke ko pe
Sibẹ ẹlomiran ki nkọ̀
Lati ma ṣe onikọ rẹ̀.
Irufẹ iwa yi ṣọwọn
Larin ẹni ọla ati ọ̀wọ̀
Bikoṣe larin awọn alafẹnujẹ,
Awọn ayajule-jẹun mọbiọbẹ dun.
Ọpa ofofo niṣẹ ẹlomiran
Si awọn aladugbo wọn.
Ẹnufitẹlẹ ati ahọn didun
Ko t' ẹgbẹ tabi ọ̀gba ri:
Alafebipa enia l' o njoye Aturọ-ta-bi-elubọ.
"Ofofo ko gb' ẹgba, ibi ọpẹ lo mọ"
Orin yi ti wọ to
Fun gbogbo eleke ati ofofo
Ẹ y' eke ṣe, eke npa ni!!!

---

AJỌ KO TU O!

A ṣe Ipade kan ni Ile-iṣẹ Ilu n... mẹta Ọsan yi ninu eyiti a pe awọ... Ọba ati awọn Ijoye si. Emi lẹ b...

# SINGER ! SINGER !! SINGER !!!




Kinla ! Tiwa ki nṣe a nṣẹṣẹ wa onibara, kini a ti ng'oku l'ọrun, nwọn pọ to wọbu larin orișirịṣi enia jakejado Nigeria.

Ẹrọ iranṣọ "SINGER" kọkan, ni gasikia polowo ara rẹ.

Pataki ohun ti o mu 'Ẹlẹha jade ọsan' ni wipe a nfẹ mu wa si akiyesi awọn ogunlọgọ onibara wa

TI ẸDINWO NLANLA TI A ṢE

ninu owo ẸRỌ IRANṢỌ wa ati IRINIṢẸ wọn, eyiti o fẹrẹ ba iye owo ti a nta wọn ki ogun Jamani to bẹrẹ nijelo mu.

Iwọnyi ni diẹ ninu awọn ohun pataki ti o jẹ ki ẸRỌ IRANṢỌ SINGER ṭ'ldi awọn ẹrọ iranṣọ miran b'omigbona.

Ikinni.—Ẹwa, itẹju ati idakẹ rọrọ l'ẹnu iṣẹ.

Ikeji.—Irọrun ti o wa lati ri orișirịṣi irin iṣẹ rẹ ti o ba bajẹ ra.

Ikẹta.—Ifọwọsọ'ya lati tunṣe nigbakugba lai gba okan gbogbo ẹrọ iranṣọ 'SINGER' ibaṣepe a ra lọdọ wa tabi ni Ẹka-ile ọja wa miran.

Wa bere iye owo wọn ni Ile-ọja wa ni Broad Street l'eko nibiti 'Ẹro Oyibiri' nl'agogo.

Phone L222, Extensions 2 & 3.
P.O. Box 171.

DADA ADESHIGBIN & SONS,
*Sole Importers Singer Sewing Machines.*

## *Open Letters.*

To Celebrities, Notorities, etc., in Different Walks of Life.

No. 19.

Mr. Charles Pilley,
Editor of *John Bull*,
Odhams Press, Ltd.
Long Acre, London, W.C. 2.
England.

Old Negrophobist,

Really, you have no idea of the low depth into which your rag—*John Bull* is rapidly sinking mainly by your idiotic sneer, cheap gibe, and *Un-British* manner in which you undertake to edit its pages.

Need I remind you that the language to which you gave vent in the paper in its issue of the 3rd instant (See Page 7) under "Coomasie Cudgers" to wit,

> "The Gold Coast niggers are still at their old game of writing to strangers asking for miscellaneous goods in return for which they promise to send African Curios" etc., etc.

is as uncouth as it is coarse? your paper's Anti-Negro sentiments dated as far back as almost the birth of that journal: would I be wrong in saying that you have shamelessly imbibed the unenviable traits of your predecessor Horatio Bottomley in your senseless, stupid and vulgar abuse of all the coloured loyal subjects of His Majesty the King, in this part of his world-wide Empire? It is not my wisn to strike a fallen man, still less is my desire to rake up old sores: but having gard to the unreasonable, hostile attitude assumed your *quondam* master against *all Africans* high low, ere his ignominious fall, it is time to ing you to your senses, and to show the utter worthlessness of your eleventh hour attempt in perpetuating race-antagonism between *Black and white*, by inditing the lines such as the above.

You will please refrain from writing offensively in your paper, bringing race-question to bear, as your continuity in the practice, will furthermore confirm the opinion held by many of your journal, that it cannot help pandering to low taste, as it is nothing short of, well, a Gutter Paper.

You are a Disgrace to the white man!!!

EKO AKETE.

Albert Cartwright Esq.,
Editor of *West Africa*,
Temple Bar House,
28, Fleet Street,
No. 20. London, E.C.4

My Valued Colleague,

Congratulations on your attaining the seventh year of the publication of your justly celebrated weekly *West Africa*, which fact became known to me in your issue of the 27th *ultimo*.

That your paper under reference, has justified its existence, since its start in the many useful ways in which it has been engaged, thereby proving itself a veritable Friend of every African at home and abroad, is a matter of common knowledge.

Many happy returns of this auspicious day!

EKO AKETE.

## THE WESLEYAN SYNOD.

*(Continued from our last.)*

On Wednesday and Friday, the closing Sessions of the Wesleyan Methodist Synod took place. Much of the business was of a routine character and of little general interest. Such matters as the attitude to be adopted towards unauthorised societies loosely connected with our Church, terms of admission of members of other Churches to the Wesleyan Methodist Church, and of Wesleyan Methodist Members to other Churches were discussed. Probationers studies for the coming year were arranged and returns were presented in order to enable the Secretary to complete his schedules.

Many years ago during a time of spiritual depression, the Conference which met at Liverpool adopted certain resolutions upon the duties of Wesleyan Methodist Ministers. Since then it has been the custom to read these resolutions, which are familiarly known as the "Liverpool Minutes" at each Annual Synod, throughout the Methodist Church, and to follow the reading with what is called "The Conversation on the work of God." This is always a time of great heart-searching, and the present occasion was no exception to the rule. The remainder of Wednesday's session was devoted to the observance of this practice and the "Conversation" was particularly helpful and inspiring. At the close the brethren joined in the Hymn "Lord in the strength of Grace" after which the Synod was adjourned until Friday in order to allow time for the preparation of the minutes.

On Friday, the Synod reassembled and received there of the Stationing Committee. The following are the chan which have been made. Rev. J. C. Cole is transferred the Staff of Wesley College, Ibadan. Rev. D. A. Bec goes to Ago, (Ijebu Mission.) Rev. D. A. Bababun Ebute-Meta, and Rev. S. A. Pearce to Oban Eko. newly received probationer, Rev. E. Ajayi Cole ha appointed to work in the Ijesa Circuit, where, we stand he will be in charge of a flourishing Ch Imesi Ipole.

It was intimated that the Missionary Collections amounted to £25 and it was agreed to divide this between the Opobo, Igbobini and Ijebu work.

The minutes of the Synod were then read and signed and according to immemorial custom the Synod came to a close with the singing of the hymn.

And let our bodies part,
To different climes repair,
Inseparably joined in heart,
The friends of Jesus are.


## WANTED.

Young lady required well educated Speaking fluently Yoruba and English to teach Yoruba about six hours a week to suit pupils convenience. Good pay for right person. Apply at 58, Palm Church Street, not later than the 15th of March, 1923, between the hours of 9 a.m. to 10 a.m. daily.

Lagos,
20th February, 1923.

## ILE OWO-ỌJA RIRANṢẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aṣoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranṣẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Ṣẹda, Onini, Owu-Ṣẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranṣọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ, ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ *(Felt)* Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kōtu, l' Eko.

## First Class Dressmaking!!!

Mrs. Said Fattal, trained in Paris, begs to offer her professional services to the public.

Latest modes at moderate charges satisfaction gauranteed. Call at once at

117, Victoria Road,
Lagos, Nigeria.



"EKO AKETE."
A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ Aṣoju wa.
Ajenifuja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.
Ọgbẹni VIDAL R. COLE.


## IGBẸ L' OWO WA.

### EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-ọ̀wọ̀ wọnyi ti gba Ọja ( *Produce* ) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya ( Niger Co.)
Jurgens Colonial,
Oyinbo Agbẹra ( Lagos Stores )
MacIver, African Products,
Association, John Holt, Miller Bros.
Patarson Zoconis,

£13 10 de £13 15 fun *ton* kan

### EPO.

£20 0 0 de £22 10 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a daruko wọnyi gba *ton* kan.

### COCOA.

Lati £20 de £22 10 fun *ton* kan bakanna.


## The Philharmonic Band.

Awọn oni fere yi nfun pẹtẹ, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn kọ pọ, nwọn ko si kọ lati lọ si ilu ki ilu.

Ẹni ba fẹ nwọn, ko kọ iwe si,

*THE SECRETARY.*
c/o Anfani Motors
The Marina Lagos.

## Mo gbe tana danu Mo gbe miran de.

Ile Egbogi ti a npe ni Iṣẹ Olodumare ti o wa ni ẹgbẹ Iga Oloye Aromirẹ ni Ọbun Eko, kun fun orişirişi awọn Egbogi wọnyi ti o şeşẹ de :—

Egbogi Kuruna, ati Ọṣẹ rẹ, Egbogi Iṣaka, Jẹdijẹdi. Ela ọmọde, Iba, Ipa ọrẹrẹ ọmọde, Egbogi Ẹda ati Aran Kiniṣa, Egbogi Inu riru iwaşu, ati fun ọkunrin pẹlu, egbogi ki ara ọkunrin le giri ( ko ma ye ẹ ) ati orişirişi awọn eyiti a ko le daruko tan.

Sare lọ sibẹ, ki ọlọra tirẹ, ọpọkuọyọku ni, bi o fẹ lori, oma dọwọ rẹ o,

" Arun ma jogun, ndagba si ẹlẹda rẹ.".

JOSHUA O. ADE: CRA[illegible]
*Alabojuto.*

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed. Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

( MORNING )

Masses Isin Aro.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

( EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

St. Michael's (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon. T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | do | do. |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. & 4 p.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J A Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity (Ebute Ero.) | Rev S J Gansallo |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev J A Leigh |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. J. Allen Angus |
| 7 p.m. | | Rev. A. N. Cole |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | | Bro J. J. Frazer |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. D. A. Beckley |
| 7 p.m. | | Rev. E. E. Williams |
| 10.30 a.m. | Obun Eko | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | | Bro. Adebiyi Tepowa |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | | Rev. M. B. Newton |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. O. Olorunjube |
| 6.30 p.m. | | Rev. E. A. Akiola |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. Samuel Ajayi |
| 4 30 p.m. | | Bro. E. A. Williams |
| 9 a.m. | Araromi (Baptist) | Rev. A. A. Puddicombe |
| 4 p.m. | | Bro. John Apena |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Rev. E. C. Alabi |
| 6.30 p.m. | Bro. J. F. Oshodi |

**BROTHERHOOD**

| | | |
|---|---|---|
| 10 a.m. | Ilupesi | S. A. Coleman Daniel |
| 7 p.m. | | Pastor A. Adedeji Iṣola |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajose ( Bamgboṣe Street. )

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon Rev. H. A. Lewis

---


"VESTA" SEWING MACHINES.

Nos. 3 and 4 Treadle on sale at No. 12 Odufẹgẹ Street, Ọbadina District Lagos.

At a giving-away price.

A call will convince you.

ALHAJI ỌLỌRUN-NI-MBE.
*General Trader*

---

W' O BI, ẸNIKEJI, OJU L' ỌRỌ WÀ!!
Maṣini Aranṣọ ti a npe ni "MUNDLOS" wa fun tita niti Ọgbẹni J. S. JOHNSON ti 16, Ita ọja Ajaṣẹ, ni owo ọpọku-ọyọku

---

Ni Ile-iwo oriṣiriṣi ọja ti
Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER,
Oniṣowo ara Jamani ni
Ita 7, Labinjo, leti Ita William

lẹ gbe le ri awọn ẹrọ RECORDS ohun orin ijọ to ṣẹṣẹ de ra ati awọn Ẹrọ wọnyi.

Ẹrọ ohun-orin GRAMOPHONE
Kẹkẹ-olo-gere BICYCLE
Awo Abọmafa ENAMELWARES
Waji BLUE ati ogunlọgọ ọja miran.
Ṣ sure tete lọ ra ti nyin nibẹ.

## SOMETHING TO YOUR TASTE.

MR. J. D. OLAYAHA, Painting Contractor and General Decorator is prepared to undertaken all paint-works of every description to the entire satisfaction of Clients.

He is also an expert in sign-board work: has worked for many important European Firms in town notably, the Firm of P. Z. and also the local P. W. D.

Terms reasonable.

For particulars,

Apply at 16, Mọgaji Lane, Ẹpẹtẹdo.

A trial will convince you.

---

## ...Ọ NI YIO ṢẸHIN DE Ẹ.

"...wa wo" "POSI Alarabara"

Ile Igbẹhin lọdọ J. T. COLE,

Gbẹna-gbẹna ni ita 40, Ofin Canal,

Ihin ko to afojuba

A le gbani ni awin ti a ba san idaji owo.

---

Are you suffering from impotent sexual & nervous prostration and impaired vitality. Use Muiracithin pills and get instant relief. It makes a man a man. In short it will rejuvenate you, also unsurpassed remedy for female Neurasthenia. Disturbed menstruation, sterlity, etc., etc. Its effect is sure and permanent, in bottle of 50 pills 5/- in bottle of 100 pills 7/- are you a sufferer of that troublesome Asthma? Why dont you use Asthamacid and get rid of it at once, in bottle 5/6. These medicines are German preparations and always give satisfactory results.

"Ajenifuja" Store — VIDAL R. COLE

P. O.Box 201; 109 — Broad Street Lagos

---

## Ọgbẹni H. CAMPOS,

Onişowo ni 7, Campbell, Street L'Eko.

...i wabiwọsi oniruru onjẹ-panu (*Provisions*) ...i tita: Ṣẹrẹkẹ ṣin ni awọn Itan-Ẹlẹde (*Hams*) ti o ni: Ọti *Wine* ati awọn Ọti miran to ni nda ni l' ọrun:

Ẹ tete lọra ti nyin nibẹ; awọn Ilẹ-ọja rẹ miran tun mbẹ ni 63, Ọdunlami Street ati 2, Onikẹpọ Street Ita Faji l'Eko

**Ohun a jẹ lo mba ni lọ.**


## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

## AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sina Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu Iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

---


## ILE EGBOGI TITUN.

Fun irọrun ati anfani gbogbo awọn ti ngbe Olowogbowo, Ita Balogun, Oke-arin Ọfin, Idumata titi lọ de Victoria Road, a şi şọbu egbogi titun kan ni Ita Balogun.

*No. 69, Balogun Street,*

Şọbu yi jẹ ẹka şọbu nla ti Filipi ni Ajẹlẹ ati Ita Faji—

*Phillips Medicine Store.*

Egbogi ojulowo pọ nibẹ.

Ma fi ọpọ silẹ nitosi lọ ra ọwọn ni ọna jijin.

---

## PAGIDARI!

*Olokiki* S. FRANCIS LAWANI *Saka-jojo.*

Onişowo ni Victoria Road ni wabi-wọsi ohun elo, fun Ọmọge ati Ọmọde-m'ẹşọ ti o si nta ni ita oloko-o-gbowo.

O si tun ni aye pataki kan ninu ile ọja na, ti a nşe Gbajamọ fun ni, ni owo-ti-kotani-lara, bi şile kan, sisi, tabi torọ.

Egbogi orişi-rişi iwosan oniruru aisan, Ipara olo-orun, ati agbọrun Jigin-oju, ati nkan mere-mere pọ to wọbu nibẹ.

Ikan-o-jọkan irin işẹ ati Egbogi ti a fi nya *Photo* aworan wa nibẹ ni ọpọku yoku.

Oniru-nru wosiwosi ti a ko le ka tan pọ nibẹ bere ohun-ko-hun ti o ba nfẹ yio pese rẹ fun ọ.

O ngbero laipẹ, lati şi ile Erọ Idan Awoşẹju ti a npe ni *(Cinema)* ni Great Bridge Street, Iduumagbo.

Şoroko a gbe şẹranwo ni igbati o ba şi ibẹ

Irohin ko to afojuba.

***P.O.Box 159*** — ***Phone 214***

## ALASE LEATHER FACTORY.

### "ILE ALAWO."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




N Awo Bata ni opoku oyoku. Kowe sowo yala ni ede Yoruba tabi ti Gesi pelu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASE
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*:—Alawobata, Eko.

---

29, Oripasin Lane,
King's Quarter, Isale Eko,
Lagos, Nigeria.

THIS IS TO CERTIFY THAT I have many years' experience in Dirty Window Cleaning, Changing of Plan Window to any colour or kind of Pattern in Flowers cleaning or white washing of wall to any kind as Distemper colour etc., Cleaning and Washing of a Dirty House to new, by Varnish and assorted kinds and Pattern of Colour to Paint House and putty and painting of Corrugated roof to red.

For Terms, etc, apply to the above address.

**Lawani T. Mogaji,**
*General Manager.*

---

Awon AWO ati IFE jojo ti a so ni "Macaulay m' Oluwa m' Oba." sese de fun tita lodo Ajibabi ni 89 Ita Apongbon l' Eko. Irufe awo ati Ife yi ko wopo. E lo ba orire nyin pade nibe. Kosi bo ti ri ni.

---

## Ogbeni ERIC. JOS. W. LEWIS.

Je enia o gba iwe-ase Ogun pipo, o si "Sahe" Egbogi Oyinbo si 14, Ita Tinubu nile ogbeni J. L. Williams Ologbe, ati si 34, Ita Obadina l'Eko. Ogbeni na setan lati da enia lohun lona ise re.

Lati *Monday* de *Saturday*.

7.30 a.m de 12.30 p.m   2 p.m de 8 p.m
Ni ojo ose lati 6.30 a.m de 8.30 a.m.
Owo to ngba ko ta enia lara, e lo bewo,
Ogun re jire.

---

## GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awon RECORDS to nkorin lede YORUBA po to wobu ni ile owo.

**MANN POOLE & COMPANY LTD.**
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nş' oku l' orun?
Ki la ti nş' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbe?

Opokuyoku si ni, wa şa eyi to wu o ni:—

**8, TINUBU SQUARE, LAGOS.**


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.